


Láti ọwọ Ààrẹ Thomas S. Monson

# Jẹ́ Àpẹrẹ àti Ìmọ́lẹ̀ kan

*Bí a ṣe ntẹ̀lé àpẹrẹ ti Olùgbàlà, tiwa yíò jẹ́ ànfàní láti jẹ́ ìmọ́lẹ̀ kan nínú ayé àwọn ẹlòmíràn.*

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin, báwo ni ó ṣe dára tó láti tún wà pẹ̀lú yín lẹ́ẹ̀kan si. Bí ẹ ṣe mọ̀, láti ìgbà tí a ti wà papọ̀ ní oṣù kẹ́rin, a ti ní ìbànújẹ́ nípa àdánù ẹni mẹ́ta lára àwọn ọlólùfẹ́ Àpọ́stélì wa: Ààrẹ Boyd K. Packer, Alàgbà L. Tom Perry, àti Alàgbà Richard G. Scott. Wọ́n ti padà sí ilé wọn ọ̀run. A se àfẹ́rí wọn . Báwo ni ìmoore wa se tó fún àpẹrẹ ìfẹ́ wọn bíi ti Krístì àti fún àwọn ìkọ́ni nípa ìmísí tí wọ́n fi sílẹ̀ fún gbogbo wa.

A nawọ́ ìkínni káàbọ̀ tọkàntọkàn sí àwọn Àpọ́stélì wa titun, Alàgbà Ronald A. Rasband, Alàgbà Gary E. Stevenson, àti Alàgbà Dale G. Renlund. Àwọn arákùnrin wọ̀nyí jẹ́ olùfarajì sí iṣẹ́ Olúwa. Wọ́n yege dáadáa láti kún àwọn àyè pàtàkì náà sí èyí tí a pè wọ́n.

Láìpẹ́ yìí, bí mo ṣe ti nkàá tí mo sì njírórò àwọn ìwé mímọ́, àwọn ẹsẹ méjì nípàtàkì ni ó ti dúró pẹ̀lú mi. Méjèèjì jẹ́ mímọ̀ sí wa. Àkọ́kọ́ jẹ́ láti inú ìwàásù lórí òkè: "Jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ rẹ kí ó tàn tó bẹ́ẹ̀ lójú àwọn ènìyàn, kí wọ́n lè rí àwọn iṣẹ́ rere rẹ, kí wọn ó sì yin Bàbá rẹ lógo tí nbẹ ní Ọ̀run."[1] Ìwé mímọ́ kejì ni ìkan tí ó wá sí mi lọ́kàn bí mo ṣe ńjíròrò ìtumọ̀ ti àkọ́kọ́. Ó wá láti inú Ìwé Kíkọ ti Páùlù Àpọ́stélì sí Tímótì: "Jẹ́ àpẹrẹ àwọm onígbàgbọ̀, nínú ọ̀rọ̀, nínú ìbánisọ̀rọ̀, nínú ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́, nínú ẹ̀mí, nínú ìgbàgbọ́, nínú ìwà mímọ́."[2]

Mo gbàgbọ́ pé ìwé mímọ́ kejì ṣe àlàyé, ní apá títóbí, bí a ṣe lè ṣe àṣeyorí ti àkọ́kọ́. A ndi àpẹrẹ àwọn onígbàgbọ́ nípa gbigbé ìgbé ayé ìhìnrere ti Jésù Krístì nínú ọ̀rọ̀, nínú ìbánisọ̀rọ̀, nínú ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́, nínú ẹ̀mí, nínú ìgbàgbọ́, àti nínú ìwà mímọ́. Bí a ṣe nṣe bẹ́ẹ̀, ìmọ́lẹ̀ wa yíò tàn fún àwọn ẹlòmíràn láti rí.

Ìkọ̀ọ̀kan lára wa wá sí ilẹ̀ ayé lẹ́hìn tí a ti gba Ìmọ́lẹ̀ Krístì. Bí a ṣe ńtẹ̀lé àpẹrẹ Olùgbàlà tí a sì ngbé bí òun ṣe gbé àti bí òun ṣe kọ́ni, ìmọ́lẹ̀ náà yíó jó nínú wa yìó sì tan ìmọ́lẹ̀ sí ọ̀nà fún àwọn ẹlòmíràn.

Àpọ́stélì Páùlù ṣe ìtòlẹ́sẹẹsẹ àwọn ìhùwàsí mẹ́fà ti onígbàgbọ́, àwọn ìhùwàsí tí yíò fi ààyè gbà àwọn ìmọ́lẹ̀ wa láti tàn. Ẹ jẹ́ kí a wo ìkọ̀ọ̀kan wọn.

Mo mẹ́nuba méjì àkọ́kọ́ papọ̀—jíjẹ́ àpẹrẹ kan nínú ọ̀rọ̀ àti ìfọ̀rọ̀wérọ̀. Àwọn ọ̀rọ̀ tí à nlò lè gbéni sókè ó sì lè mísíni , tàbí wọ́n lè ṣeni léṣe àti pé kí wọ́n rẹ̀ni sílẹ̀. Nínú ayé lóní ọ̀pọ̀ ìsọkúsọ wà pẹ̀lú èyí tí ó dàbíi pé ó yíwa po ní gbogbo ìgbésẹ̀. Ó ṣòro láti yẹra fún gbígbọ́ àwọn orúkọ ti Ọlọ́run ní lílò lásán àti láìní ìrònú. Àwọn ìsọ̀rọ̀ líle dàbíi pé ó ti di ohun tí ó wọ́pọ̀ lórí ẹ̀rọ amóhùnmáwòrán, àwọn eré ìtàgé, àwọn ìwé, àti orin. Ìbáraẹnisọ̀rọ̀ ní àyíká jẹ́ ìsọ̀rọ̀sí àbùkù ati ọ̀rọ̀ ìríra tí ó ní ìbínú. Ẹ jẹ́ kí a sọ̀rọ̀ sí àwọn ẹlòmíràn pẹ̀lú ìfẹ́ àti ọ̀wọ̀, kí a máa pa àwọn èdè wa mọ́ ní mímọ́ kí a sì yẹra fún àwọn ọ̀rọ̀ tàbí àwọn ìsọ̀rọ̀ tí ó lè ṣenilẹ́ṣe tàbí múni ṣẹ̀. Njẹ́ kí a lè tẹ̀lé àpẹrẹ ti Olùgbàlà, ẹnití ó sọ̀rọ̀ pẹ̀lú ìpamọ́ra àti inúrere ní gbogbo iṣẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀.

Ìhùwàsí tí ó tẹ̀le èyí tí Páùlù mẹ́nubà ni ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́, èyí tí a túmọ̀ sí bíi "ìfẹ́ àìllẹ́gbẹ́ ti Krístì."[3] Mo ní ìdánilójú pé nínú agbára àyíká wa a ní àwọn àdánìkanwà , àwọn tí wọ́n nṣàìsàn, àti àwọn wọ̃nnì tí wọ́n ní ìmọ̀lara ìrẹ̀wẹ̀sì. Tiwa ni ànfàní láti ràn wọ́n lọ́wọ́ àti láti fún ọkàn wọn ní ìgbéga. Olùgbàlà mú ìrètí wá fún àwọn aláìnírètí ati okun fún àwọn aláìlera . Ó wo aláìsàn sàn; Ó mú kí arọ rìn, kí afọ́jú ríran, kí adití gbọ́ran. Àní Ó jí òkú dìde sí áyé. Ní gbogbo iṣẹ́ ìránṣẹ́ Rẹ̀ Ó nawọ́ jáde nínú ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́ sí ẹnikẹ́ni nínú àìní. Bí a ṣe ńtẹ̀lé àpẹrẹ Rẹ̀, a ó bùkún àwọn ìgbé ayé, àti tiwa pẹ̀lú.

Èyí tí ó kàn, a níláti jẹ́ àpẹrẹ nínú ẹ̀mí. Sí mi èyíinì túmọ̀ sí pé à ńtiraka láti ní inúrere, ìmoore, ìdáríjì, àti èrò rere nínú ìgbé ayé wa. Àwọn ìwà wọ̀nyí yíò pèsè ẹ̀mí kan fún wa èyí tí yíò fọwọ́kan ìgbé ayé àwọn wọ̃nnì ní àyíká wa. Ó ti jẹ́ ànfàní fún mi lati ọdún dé ọdún láti ní ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú àìlónkà àwọn ẹnìkọ̀ọ̀kan tí ó ní irú

ẹ̀mí yìí. A ní ìrírí ìmọ̀lára pàtàkì kan nígbàtí a bá wà pẹ̀lú wọn, ìmọ̀lára tí ó nmú wa fẹ́ láti bá wọn ṣe àti láti tẹ̀lé àpẹrẹ wọn. Wọ́n ntan ìmọ́lẹ̀ ti Krístì wọ́n sì nràn wá lọ́wọ́ láti ní ìmọ̀lára ìfẹ́ Rẹ̀ fún wa.

Láti ṣe àpèjúwe pé ìmọ́lẹ̀ èyí tí ó ńwá láti ara ẹ̀mí aláìléeri àti onífẹ̀ẹ́ máa njẹ́ dídámọ̀ fún àwọn ẹlòmíràn , èmi ó sọ fún yín nípa ìrírí mi kan ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́hìn.

Ní ìgbà náà, àwọn olórí Ìjọ pàdé pẹ̀lú àwọn òṣìṣẹ́ ní Jérúsálẹ́mù láti ṣe àdéhùn ìyọ̀nda ilẹ̀ lórí èyítí Gbàgede Ìjọ ti Jérúsálẹ́mù yíó dí kíkọ́. Ní èrò láti gba àṣẹ tí a nílò, Ìjọ níláti fi ọwọ́ síi pé ìkéde ìhìnrere kankan kì yíó jẹ́ ṣíṣe lati ọwọ́ àwọn ọmọ ìjọ tí yíò wà nínú gbàgede náà. Lẹ́hìn tí a ti ṣe àdéhùn náà, ọ̀kan lára àwọn òṣìṣẹ́ Ísráẹ́lì náà, ẹnití ó mọ ìjọ àti àwọn ọmọ ìjọ dáadáa, sọ̀rọ̀ pé òun mọ pé Ìjọ yíò bu iyì fún àdéhùn àìsí ìkéde ìhìnrere náà. "Ṣùgbọ́n," ó sọ, ní ìtọ́kasí sí àwọn ọmọ ilé ìwé tí yíó lọ síbẹ̀, "kíni àwà yíò ṣe nípa ìmọ́lẹ̀ tí ó wà ní ojú wọn?"[4] Njẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ pàtàkì náà lè máa tàn nínú wa láé, kí àwọn ẹlòmíràn lè dáamọ̀ kí wọn ó sì mọ iyì rẹ̀.

Láti jẹ́ àpẹrẹ ìgbàgbọ́ túmọ̀ sí pé a ní ìgbẹ́kẹ̀lé nínú Olúwa àti nínú ọ̀rọ̀ Rẹ̀. Ó túmọ̀ sí pé a ní àti pé a nṣe ìtọ́jú àwọn ìgbàgbọ́ náà tí yíò ṣe ìtọ́sọ́nà fún àwọn èrò wa àti àwọn ìṣe wa. Ìgbàgbọ́ wa nínú Olúwa Jésù Krístì àti Bàbá wa Ọ̀run yíò fi agbára sí gbogbo ohun tí a bá ṣe. Ní àárín ìdààmú ti ọjọ́ wa, àwọn ìjà ẹ̀rí ọkàn, àti agara ìgbé ayé ojojúmọ́, ìgbàgbọ́ dídúró-ṣinṣin di ìdákọ̀ró sí ayé wa. Rántí pé ìgbàgbọ́ àti iyèméjì kò lè wà ní inú iyè kannáà nígbàkannáà, nítorí ọ̀kan yíò mú èkejì kúrò. Mo ṣe àtẹnumọ́ ohun tí a ti sọ fúnwa ní àsọtúnsọ—pé kí a lè baà jèrè àti láti pa ìgbàgbọ́ tí a nílò mọ́, ó ṣe pàtàkì pé kí a kàá kí a sì ṣe àṣàrò àti pé kí a jíròrò lórí àwọn ìwé mímọ́. Ìbásọ̀rọ̀ pẹ̀lú Bàbá wa Ọ̀run nípasẹ̀ àdúrà ṣe kókó. A kò leè fi àwọn ohun wọ̀nyí sílẹ̀ ní pípatì, nítorí ọ̀tá àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ nfi àìsimi wá àlàfo lára ìhámọ́ra wa, ìfàsẹ́hìn kan nínú ìgbàgbọ́ wa. Olúwa sọ pé, "ṣe àwárí pẹ̀lú aápọn, gbàdúrà nígbàgbogbo, kí o sì gbàgbọ́, àti pé ohun gbogbo yíò ṣiṣẹ́ papọ̀ fún rere rẹ."[5]

Ní ìparí, a níláti wà ni àìlẽrí, èyí tí ó túmọ̀ sí pé a mọ́ ní ara, inú, àti ẹ̀mí. A mọ̀ pé ara wa jẹ́ tẹ́mpìlì, tí a níláti tọ́jú pẹ̀lú bíbu ọlá àti ọ̀wọ̀ fún. Inú wa gbọ́dọ̀ kún fún àwọn èrò tí ó ngbéniga àti tí ó nbu ọlá fúnni kí ó sì pa mọ́ kúrò nínú àwọn ohun wọ̀nnì èyí tí yíò sọọ́ di àìmọ́. Kí á baà lè ní Ẹ̀mí Mímọ́ gẹ́gẹ́bí ẹnìkejì wa nígbà-gbogbo, a gbọ́dọ̀ jẹ́ yíyẹ. Ẹyin arákùnrin àti arábìnrin, ìwà mímọ́ yíò mú ìbàlẹ̀ ọkàn wá fún wa yíò sì mú wa yege láti gba àwọn ìlérí Olùgbàlà. Ó sọ pé, "Alábùkúnfun ni àwọn ọlọ́kàn mímọ́: nítorí wọn yíò rí Ọlọ́run."[6]

Bí a ṣe nfihàn pé a jẹ́ àpẹrẹ nínú ọ̀rọ̀, nínú ìbánisọ̀rọ̀, nínú ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́, nínú ẹ̀mí, nínú ìgbàgbọ́, àti nínú ìwà mímọ́, a ó yege láti jẹ́ ìmọ́lẹ̀ sí aráyé.

Njẹ́ kí nsọ fún gbogbo yín, àti nípatàkì sí ẹ̀yin ọ̀dọ́, pé bí ayé ṣe nyí síwájú àti síwájú kúrò nínú àwọn ẹ̀kọ́ àti àwọn ìtọ́nisọ́nà tí a fi fúnni láti ọwọ́ ọlólùfẹ́ Bàbá wa Ọ̀run, a ó dúró ní pípéye kúrò nínú àwọn èrò nítorípé a yàtọ̀. A ó dúró ní pípéye nítorípé a ńwọṣọ ní ìwọ̀ntún-wọ̀nsì. A ó yàtọ̀ nítorí a kò lo àwọn ọ̀rọ̀ àìlọ́wọ̀ àti nítorípé a kò ṣe alábápín àwọn ohun èyí tí ó léwu sí ara wa. A ó yàtọ̀ nítorípé à nyẹra fún àpárá tí kò bánimu àti àwọn ọ̀rọ̀ tí nsọni di yẹpẹrẹ. A ó yàtọ̀ bí a ṣe pinnu láti máṣe kún inú wa pẹ̀lú àwọn àṣàyàn ìròhìn tí kò nílárí tí ó sì buni kù àti tí yíò mú Ẹ̀mí kúrò nínú ilé wa àti ní ìgbé ayé wa. Dájúdájú a ó dúró ní pípé bí a ṣe nṣe àṣàyàn nípa ìhùwàsí—àwọn àṣàyàn wọ̃nnì èyí tí ó somọ́ àwọn ẹ̀kọ́ ìhìnrere àti àwọn ìdiwọ̀n. Àwọn ohun wọ̃nnì èyí tí ó mú wa yàtọ̀ sí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ní ayé, bákannáà ó npèsè wa pẹ̀lú ìmọ́lẹ̀ náà àti ẹ̀mí náà èyítí yíò tàn nínú ayé tí dúdú rẹ̀ ńgbòòrò síi.

Ó máa nṣòro nígbàgbogbo láti yàtọ̀ àti láti dá dúró láàrin ọ̀pọ̀ èrò. Ó jẹ́ àdánidá láti bẹ̀rù ohun tí àwọn míràn lè rò tàbí sọ. Ìtùnú ni àwọn ọ̀rọ̀ ti Orin Dáfídì: "Olúwa ni ìmọ́lẹ̀ mi àti ìgbàlà mi; tani èmi ó bẹ̀rù? Olúwa ni agbára ẹ̀mí mi; àyà taani yíò fò mí?"[7] Bí a ṣe nfi Krístì sí oókan ìgbé ayé wa, àwọn ẹ̀rù wa yíò di rírọ́pò pẹ̀lú ìdánilójú ìgbàgbọ́ wa.

Ìgbé ayé kò pé fún ẹnìkẹ́ni nínú wa, àti pé ní àwọn ìgbà míràn àwọn ìpèníjà àti ìṣòro tí à ńdojúkọ le fẹ́ bòwámọ́lẹ̀, ó sì nfa kí ìmọ́lẹ̀ wa ṣókùnkùn. Bí ó tilẹ̀ ríbẹ̃ẹ̀, pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ láti ọ̀dọ̀ Bàbá wa Ọ̀run, ní àsopọ̀ pẹ̀lú àtìlẹhìn láti ọ̀dọ̀ àwọn míràn, a tún le jèrè ìmọ́lẹ̀ náà èyí tí yíò tàn sí ipa ọ̀nà ti ara wa lẹ́ẹ̀kansíi tí yíò sì pèsè ìmọ́lẹ̀ tí àwọn míràn lè nílò.

Láti ṣe àpèjúwe, èmi ó ṣe àbápín pẹ̀lú yín àwọn ọ̀rọ̀ kan tí ó kanni, nípa ewì wíwuni kan tí mo kọ́kọ́ kà ní ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún sẹ́hìn:

*Mo pàdé àlejò kan ní òru*
*Ẹnití àtùpà rẹ̀ ti dúró ní títàn.*
*Mo dáradúró mo sì jẹ́ kí ó tanná*
*Sí àtùpà rẹ̀ láti ọ̀dọ̀ tèmi.*

*Ìjì líle kan rú sókè lẹ́hìn náà*
*Ó sì mi ayé káàkiri.*
*Àti pé nígbàtí ìjì náà lọ*
*Àtùpà mi ti kú!*

*Ṣùgbọ́n àlejò náà padà sí ọ́dọ̀ mi—*
*Àtùpà rẹ̀ ntàn dáadáa!*
*Ó di ìtànná iyebíye náà mú*
*Ó sì tàn tèmi!*[8]

Ẹyin arákùnrin àti arábìnrin mi, àwọn ànfàní wà fúnwa láti tan ìmọ́lẹ̀ sí àyíká wa lójoojúmọ́, ní irú èyíkéyí ipò tí a bá bá ara wa. Bí a ṣe ntẹ̀lé àpẹrẹ ti Olùgbàlà, tiwa ni ànfàní náà láti jẹ́ ìmọ́lẹ̀ sí ìgbé ayé àwọn ẹlòmíràn, bóyá wọ́n jẹ́ ọmọlẹ́bí tiwa àti àwọn ọ̀rẹ́, àwọn ará ibi iṣẹ́, àwọn olùbárẹ́ lásan, tàbí àwọn àjèjì pátápátá.

Sí ọ̀kọ̀ọ̀kan yín mo sọ pé ẹ jẹ́ ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin ti Bàbá wa Ọ̀run. Ẹ ti wá láti ọ̀dọ̀ Rẹ̀ láti gbé lórí ilẹ̀ ayé yìí fún àsìkò kan, láti ronú nípa ìfẹ́ àti àwọn ìkọ́ni Olùgbàlà, àti láti fi ìgboyà-ìgboyà jẹ́ kí ìmọ́lẹ̀ yín tàn fún gbogbo ènìyàn láti rí. Nígbàtí àsìkò náà lórí ilẹ̀ ayé bá parí, tí ẹ bá ti sa ipá yín, tiyín yíó jẹ́ ìbùkún ológo ti pípadà láti gbé pẹ̀lú Rẹ̀ títíláé.

Báwo ni àwọn ọ̀rọ̀ Olùgbàlà ṣe jẹ́ dídánilójú tó: "Èmi ni ìmọ́lẹ̀ ayé: ẹni tí

ó bá tẹ̀lé mi kò ní rìn nínú òkùnkùn, ṣùgbọ́n yíò ní ìmọ́lẹ̀ ìyè.”[9] Nípa Rẹ̀ ni mo jẹ́rí. Òun ni Olùgbàlà àti Olùràpadà wa, Alágbàwí wa pẹ̀lú Bàbá. Òun ni Alápẹrẹ wa àti okun wa. Òun ni “ìmọ́lẹ̀ tí ó ntàn nínú òkùnkùn.”[10] Pé kí ọ̀kọ̀ọ̀kan wa lábẹ́ ìró ohùn mi lè jẹ́jẹ̀ẹ́ láti tẹ̀lé E, nípa bẹ́ẹ̀ kí wọn ó le di ìmọ́lẹ̀ tí ó ntàn sí ayé, àní Jésù Krístì Olúwa, àmín.


**ÀWỌN ÀKỌSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́**

1. Matteu 5:16
2 1 Timothy 4:12
3 Moroni 7:47
4 Wo James E. Faust, “Ìmọ́lẹ̀ nínú Ojú Wọn,”
5 ẸkọàtiÀwọnMájẹmú 90:24
6 Matteu 5:8
7 OrinDáfídì 27:1
8 Lon Woodrum, “Àwọn Ògùṣọ̀,”*Ipá Ọ̀nà Mímọ́-lẹ̀*Oct. 1940, 17
9 Johannu8:12
10 ẸkọàtiÀwọnMájẹmú6:21



## Àwọn Ìkọ́ni fún Ìgbà Tiwa

Láti oṣù kọkànlá ọdún 2015 sí oṣù kẹrin ọdún 2016 àwọn ẹkọ ti Oyè àlùfáà Mẹlkisédékì àti Ẹgbẹ Ìrànlọ́wọ ní ọjọ ìsinmi kẹrin ni a niláti múra rẹ sílẹ láti inú ìkan tàbí jùbẹẹ lọ lára àwọn ọ̀rọ̀ tí a fi fúnni ní ìpàdé gbogbogbòò ti oṣù kẹwàá ọdún 2015 Ní oṣù kẹrin ọdún 2016 a lè yan àwọn ọrọ bóyá láti inú ìpàdé gbogbogbòò oṣù kẹrin ọdún 2016 tàbí oṣù kẹwàá ọdún 2015 Àwọn Ààrẹ Eèkànàti Ẹkùngbọ́dọ̀yanàwọnọ̀rọ̀èyítíwọnyíòlòníagbègbèwọn, tàbíwọnlègbéojúṣeyíléàwọn Bíṣọọpùàtiàwọnààrẹekalọ́wọ

Àwọnọrọnáàwàníonírũrúèdèníconference.lds.org


© 2015 Láti Ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ ìtumọ̀: 6/15.


Ìtumọ̀ ti *First Presidency Message, November 2015.* Yoruba. 12591 779



**Láti ọwọ́ Ààrẹ Henry B. Eyring**
Olùdámọ̀ràn Kínní nínú Àjọ Ààrẹ Ìkínní

# Ẹ̀mí Mímọ́ gẹ́gẹ́bí Ojúgbà Yín

*A lè ní ìbùkún ti Ẹ̀mí láti wà pẹ̀lú wa, bí a bá gbé ní yíyẹ fún un, kìí ṣe nísìnyìí àti lẹ́hìnnáà nìkan ṣùgbọ́n ní gbogbo ìgbà.*

Ẹ̀yin arákùnrin àti arábìnrin mi ọ̀wọ́n, mo fi ìmoore hàn láti wà pẹ̀lú yín ní Ọjọ́ Ìsinmi yí nínú ìpàdé gbogbogbòò ti Ìjọ Olúwa. Mo ti ní ìmọ̀lára ti Ẹ̀mí, bí ẹ̀yin náà ti ní, , Ẹ̀mí Mímọ́, tí ó njẹ́rí sí àwọn ọ̀rọ̀ òtítọ́ tí a ti gbọ́ ní síso àti ní kíkọ lórin.

Èrò mi lóní ni láti mú kí ìfẹ́ yín àti ìpinnu yín pọ̀ síi láti gba ẹ̀bùn tí a ṣe ìlérí rẹ̀ fún ọ̀kọ̀ọ̀kan wa lẹ́hìn tí a ti ṣe ìrìbọmi. Ní ìgbà ìfẹsẹ̀múlẹ̀ wa a gbọ́ àwọn ọ̀rọ̀ wọ̀nyí: "Gba Ẹ̀mí Mímọ́."[1] Láti àsìkò náà, ayé wa yípadà láéláé.

A lè ní ìbùkún ti Ẹ̀mí, láti wà pẹ̀lú wa, bí a bá gbé ní yíyẹ fún un, kìí ṣe nísìsìyìí àti lẹ́hìnnáà nìkan, bí nínú irú àwọn ìrírí olókìkí bí a ṣe ní lóní, ṣùgbọ́n ní gbogbo ìgbà. Ẹ mọ̀ láti inú àwọn ọ̀rọ̀ àdúrà oúnjẹ Olúwa bí ìlérí náà ṣe di mímúṣẹ: "Aa Ọlọrun Bàbá Ayerayé awá bèèrè lọwọ rẹ ni orukọ Ọmọ rẹ, Jesu Kristi pé, lati bukun kí ẹ sì yà búrẹ́dì yìí sí mimọ fún ọkan gbogbo àwọn tí ó jẹ ninu rẹ láti lè jẹ ní ìrántí ara ti Ọmọ rẹkí wọn ó sì jẹri sí Ọ, Aa Ọlọrun Bàbá Ayerayé pé wọn ní ìfẹ lati gba orúkọ Ọmọ rẹ sí órí wọn kí wọn sì rántí rẹ nígbàgbogbo kí wọn sì pa ofin rẹ mọ èyí tí ti ó ti fifun wọn."

Àti pé nígbànáà ní ìlérí ológo náà wá pé: "Pé kí wọn lè*ní ẹ̀mí rẹ̀ pẹ̀lú wọn*nígbàgbogbo" (D&C 20:77; àfikún Àtẹnumọ́).

Láti ní Ẹ̀mí náà pẹ̀lú wa nígbàgbogbo ni láti ní ìtọ́sọ́nà àti ìdarí Ẹ̀mí Mímọ́ nínú ayé wa lójojúmọ́. A lè, fún àpẹrẹ, gba ìkìlọ̀ nípasẹ̀ Ẹ̀mí láti tako àdánwò láti ṣe ibi.

Fún èrèdí yí nìkan, ó rọrùn láti rí ìdí tí àwọn ìránṣẹ́ Olúwa ṣe ntiraka láti mú kí ìfẹ́ wa láti sin Ọlọ́run pọ̀ si nínú àwọn ìpàdé oúnjẹ Olúwa. Tí a bá ṣe àlábápín oúnjẹ Alẹ́ Olúwa nínú ìgbàgbọ́, nígbànáà Ẹ̀mí Mímọ́ yíò lè dáàbò bò wá àti àwọn wọnnì tí a fẹ́ràn láti inú àwọn idánwò tí ó ńwá pẹ̀lú ọ̀pọ̀ ipá àti ní léraléra.

Jíjẹ́ ojúgbà ti Ẹ̀mí Mímọ́ nmú ohun tí ó dára láti dára síi àti pé ó nmú ìfipámúni ìdánwò dínkù. Èyí nìkan gbọ́dọ̀ tó láti mú wa pinnu láti yege fún Ẹ̀mí láti wà pẹ̀lú wa nígbàgbogbo.

Gẹ́gẹ́bí Ẹ̀mí Mímọ́ ṣe ńfún wa lókun ní ìlòdì sí ibi, Ó nfún wa ní agbára bákannáà láti mọ yàtọ̀ ní ààrín òtítọ́ àti irọ́ pípa. Òtítọ́ tí ó wúlò jù ni a fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ nípa ìfihàn láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run. Èrò wa bíi ènìyàn àti lílò ọgbọ́n ti ara wa kò lè tó. À ngbé ní àsìkò kan àní nígbàtí yíò ṣòro gidi fún ẹnití ó gbọ́n jùlọ láti mọ̀ ìyàtọ̀ òtítọ́ kúrò nínú ọgbọ́n ẹ̀tàn.

Olúwa kọ́ Àpóstélì Rẹ̀ Thomas, ẹnití ó fẹ́ ẹ̀rí ti ara nípa Àjíǹde Olùgbàlà nípa fífi ọwọ́ kan àwọn ọgbẹ́ Rẹ̀, pé ìfihàn jẹ́ ẹ̀rí tí ó ní ààbò jù: "Jésù wí fún un, Thomas, nítorítí ìwọ rí mi, ni ìwọ ṣe gbàgbọ́: alábùkún fún ni àwọn tí kò rí mi, tí wọ́n sì gbàgbọ́" ( John 20:29).

Àwọn òtítọ́ tí ó ṣe àmì sí ọ̀nà ilé sí ọ̀dọ̀ Ọlọ́run ni a fi ẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ nípa Ẹ̀mí Mímọ́. A kò lè lọ sí igbó kékeré kí a sì rí Bàbá àti Ọmọ tí wọ́n sọ̀rọ̀ sí ọ̀dọ́mọdé Joseph Smith. Kò sí ẹ̀rí ti ara tàbí àríyànjiyàn ọgbọ́n inú tí ó lè ṣe àgbékalẹ̀ pé Èlíjàh wá gẹ́gẹ́bí ìlérí láti gbé àwọn kọ́kọ́rọ́ oyè àlùfáà léni lọ́wọ́ tí wọ́na dìmú nísisìyìí àti èyí tí a nṣe lílò rẹ̀ nípasẹ̀ wòlíì alàáyè, Thomas S. Monson.

Ìfẹsẹ̀múlẹ̀ òtítọ́ nwá sí ọ̀dọ̀ ọmọkùnrin tàbí ọmọbìnrin Ọlọ́run tí ó ti gba ẹ̀tọ́ náà láti gba Ẹ̀mí Mímọ́. Níwọ̀n ìgbà tí wọ́n ti lè gbé àwọn ẹ̀tàn àti irọ́ pípa síwájú wa nígbàkugbà, a nílò agbára ti Ẹ̀mí Òtítọ́ léraléra láti mú àsìkò iyèméjì wa kúrò.

Nígbàtí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ Iyejú àwọn Àpóstélì Méjìlá, George Q. Cannon rọ̀ wá láti ṣe ìbèèrè léraléra fún Ẹ̀mí láti wà pẹ̀lú wa. Ó ṣe ìlérí, èmi náà sì ṣe ìlérí bákannáà pé, tí a bá lépa ọ̀nà náà, a "kò ní ṣaláìní ìmọ̀" ti òtítọ́, "a kò ní wà nínú ìṣiyèméjì tàbí nínú òkùnkùn," àti pé "ìgbàgbọ́ wa yíò le, ayọ̀ [wa] yíò . . . kún."[2]

A nílò ìrànlọ́wọ́ léraléra láti inú jíjẹ́ ojúgbà ti Ẹ̀mí Mímọ́ fún ìdí míràn bẹ́ẹ̀.

Ikú ti olólùfẹ́ kan lè wá láìròtẹ́lẹ̀. Ó jẹ́ ẹ̀rí láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ nípa jíjẹ́ òdodo ti olólùfẹ́Bàbá wa Ọ̀run àti Olùgbàlà tí ó jíìnde ni ó ńfún wa ní ìrètí àti ìtùnú ní ìpàdánù olùfẹ́ni kan. Ẹ̀rí náà gbọ́dọ̀ jẹ́ tuntun nígbàtí ikú bá ṣẹlẹ̀.

Nítorínáà, fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdí, a nílò jíjẹ́ ojúgbà ti Ẹ̀mí Mímọ́ léraléra. A fẹ́ ẹ, ṣùgbọ́n síbẹ̀síbẹ̀ a mọ̀ nípa ìrírí pé kò rọrùn láti ṣe ìtọ́jú rẹ̀. Ọ̀kọ̀ọ̀kan wa nrò, nsọ, a sì nṣe àwọn ohun nínú ayé wa tí ó lè mú Ẹ̀mí bínú. Olúwa kọ́ wa pé Ẹ̀mí Mímọ́ yíò jẹ́ olùrànlọ́wọ́ wa lemọ́lemọ́ nígbàtí ọkàn wa bá kún fún ìfẹ́ àìlẹ́gbẹ́ àti nígbàtí "ìwà rere bá [ti] ṣe èrò [wa lọ́ṣọ́ láìsimi"(wo D&C 121:45)

Fún àwọn wọnnì tí wọ́n nlàkàkà pẹ̀lú ọ̀ṣùwọ̀n gíga tí a nílò láti yege fún ẹ̀bùn ti ìrànlọ́wọ́ Ẹ̀mí, mo fún yín ní ìgbìyànjú yí. Ẹ ti ní àwọn ìgbà tí ẹ ti ní ìmọ̀lára agbára ti Ẹ̀mí Mímọ́. Ó lè ti ṣẹlẹ̀ fún yín lóní

O lè tọ́jú àwọn àsìkò ìmísí wọnnì bíi ti èso ìgbàgbọ́ tí Álmà ṣe àpèjúwe rẹ̀ (wo Álmà 32:28). Gbin ìkọ̀ọ̀kan. Ẹ lè ṣe èyí nípa ṣíṣe iṣẹ́ lórí ìṣílétí tí ẹ ní ìmọ̀lára rẹ̀. Ìmísí tí ó níye lórí jùlọ yíò jẹ́ fún yín láti mọ ohun tí Ọlọ́run yíò fẹ́ kí ẹ ṣe. Tí ó bá jẹ́ sísan ìdámẹ́wá, tàbí bíbẹ ọ̀rẹ́ kan ti ó nṣọ̀fọ̀ wò, ẹ níláti ṣeé. Ohunkóhun tí ó bá jẹ́, ẹ ṣeé. Nígbàtí ẹ bá fi ìfẹ́ yín hàn láti gbọ́ran, Ẹ̀mí yíò túbọ̀ rán àwọn ìtẹ̀mọ́rasíi yín nípa ohun tí Ọlọ́run yíò fẹ́ kí ẹ ṣe fún Òun .

Bí ẹ ṣe ngbọ́ran, àwọn ìtẹ̀mọ́ra láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀mí yíò máa wá léraléra, yíò di sísúnmọ́ àti sísúnmọ́ sí jíjẹ́ ojúgbà léraléra. Agbára yín láti yan èyí tí ó tọ́ yíò pọ̀ síi.

O lè mọ̀ nígbàtí àwọn ìtẹ̀mọ́ra láti ṣe ìṣe bá wá láti ọ̀dọ̀ Ẹ̀mí ju láti inú ìfẹ́ ti ara yín. Nígbàtí àwọn ìtẹ̀mọ́ra bá wà ní ìbámu pẹ̀lú ohun tí Olùgbàlà àti àwọn wòlíì alààyè Rẹ̀ àti àwọn àpóstélì ti sọ, ẹ̀yin lè yàn láti gbọ́ran pẹ̀lú ìgbẹ́kẹ̀lé. Nígbànáà Olúwa yíò rán Ẹ̀mí Rẹ̀ láti ràn yín lọ́wọ́.

Fún àpẹrẹ, tí ẹ bá gba ìtẹ̀mọ́ra ti ẹ̀mí kan láti bu ọlá fún ọjọ́ Ìsinmi, nípàtàkì nígbàtí ó dàbíí pé ó ṣòro, Ọlọ́run yíò rán Ẹ̀mí Rẹ̀ láti ṣèrànwọ́.

Ìrànlọ́wọ́ náà wá sí ọ̀dọ̀ bàbá mi ní ọ́dún díẹ̀ sẹ́hìn nígbàtí iṣẹ́ rẹ̀ gbe wá sí Australia. Ó dá wà ní ọjọ́ Ìsinmi kan, ó sì fẹ́ láti gba oúnjẹ alẹ́ Olúwa. Kò lè rí ìwífúnni kankan nípa àwọn ìpàdé Ènìyàn Mímọ́ ọjọ́ ìkẹhìn. Nítorínáà ó bẹ̀rẹ̀ sí nrìn. Ó gbàdúrà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan ìkórita láti mọ ọ̀nà èyí tí yíò yí sí. Lẹ́hìn rírìn àti ṣíṣe àyípo fún wákàtí kan, ó dúró láti gbàdúrà lẹ́ẹ̀kansi. Ó ní ìmọ̀lara ìtẹ̀mọ́lẹ̀ láti yí sí ìsàlẹ̀ òpópónà kan pàtó. Láìpẹ́ ó bẹ̀rẹ̀ sí ńgbọ́ orin tí ó ńwá láti ìsàlẹ̀ ilé kan nítòsí. Ó wo inú ilé láti ojú fèrèsé ó sì rí àwọn ènìyàn díẹ̀ tí wọ́n jókó lẹ́gbẹ́ tábìlì kan tí wọ́n fi aṣọ funfun kan bò àti àwọn ọpọ́n oúnjẹ Alẹ́ Olúwa.

Báyìí, èyí lè má dàbí nkan tí ó pọ̀ síi yín, ṣùgbọ́n ó jẹ́ ohun kan tó yanilẹ́nu sí òun . Ó mọ pé ìlérí ti àdúrà oúnjẹ Olúwa ti wá sí ìmúṣẹ: : "Máa rántí rẹ̀ nígbàgbogbo kí wọ́n ó sì máa pa àwọn òfin rẹ̀ mọ́ èyí tí ó ti fún wọn; kí wọ́n lè ní Ẹ̀mí rẹ̀ lati wà pẹ̀lú wọn nígbàgbogbo" ( D&C 20:77).

Èyí ni àpẹrẹ kan ṣoṣo ti ìgbàtí ó gbàdúrà nígbànáà tí ó ṣe ohun tí Ẹ̀mí sọ fun pé Ọlọ́run fẹ́ kí o ṣe. Ó tẹra mọ́ ṣíṣeé fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdún, bí ìwọ àti èmi yíò ti ṣe. Kò fi ìgbà kankan sọ̀rọ̀ nípa ipò ti ẹ̀mí rẹ̀. Ó kan tẹ́ramọ́ ṣíṣe àwọn ohun kékèèké fún Olúwa tí ó ní ìṣílétí lati ṣe.

Nígbàkugbà tí àwọn ẹgbẹ́ àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn díẹ̀ bá bèèrè pé kí ó bá wọn sọ̀rọ̀, ó ṣeé. Kò pọndandan bí ó tilẹ̀ jẹ́ ènìyàn mẹ́wá tàbí àádọ́ta tàbí bí ó ṣe rẹ̀ẹ́ sí. Ó jẹ́ ẹ̀rí rẹ̀ nípa Bàbá, Ọmọ, Ẹ̀mí Mímọ́, àti nípa àwọn wòlíì nígbàkugbà tí Ẹ̀mí bá rọ̀ọ́ láti ṣeé.

Àwọn ìpè rẹ̀ tí ó ga jùlọ nínú Ìjọ ni sí ìgbìmọ̀ gíga ti Èèkàn Bonneville Utah, níbi tí ó ti géko lórí okò èèkàn, ó sì kọ́ yàrà ìkọ̀wé kan ní Ilé Ẹ̀kọ́ ọjọ́ Ìsinmi. Ní àwọn ọdún púpọ̀, nígbàtí ó bá nílò rẹ̀, Ẹ̀mí Mímọ́ wà níbẹ̀ gẹ́gẹ́bí ojúgbà rẹ̀.

Mo dúró lẹ́gbẹ́ bàbá mi ní yàrá kan nílé ìwòsàn. Ìyá mi, ìyàwó rẹ̀ fún ọgọ́jì ọdún ólé kan, sùn sórí ibùsùn. A ti wòó fún ọ̀pọ̀ wákàtí. A bẹ̀rẹ̀ sí ńrí àwọn ìlà ìrora tí ó nkúrò lójú rẹ̀. Àwọn ìka ọwọ́ rẹ̀, èyí tí o tí dìpọ̀ sí ìkúùkù, ti dẹwọ́. Ọwọ́ rẹ̀ wá láti sinmi sí ẹ̀gbẹ́ rẹ̀.

Àwọn ìrora ti àwọn ọdún mẹ́wámẹ́wàá àrùn jẹjẹrẹ ti ndópin. Mo rí ìwò àláfíà ní ojú rẹ̀. Ó mí àwọn èémí kíkúrú díẹ̀, nígbànáà ó fi ìtàra mí, àti pé nígbànáà ó sùn jẹ́jẹ́ . A dúró síbẹ̀ a nretí bóyá èèmí míràn yíó tún wá.

Nígbẹ̀hìn, Bàbá sọ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ pé, "Ọmọdébìnrin kékeré ti lọ sílé."

Kò sọkún rárá. Èyí jẹ́ nitorí pé tipẹ́tipẹ́ ni Ẹ̀mí Mímọ́ ti fún un ní àwòrán yékéyéké nípa ẹni tí ó jẹ́, ibi tí ó ti wá, ohun tí ó ti dà, àti ibi tí ó nlọ. Ẹ̀mí náà ti jẹ́ ẹ̀rí sí i nígbà púpọ̀ nípa olùfẹ́ni Bàbá Ọ̀run, nípa Olùgbàlà ẹnití ó ti ṣẹ́gun agbára ikú, àti ti jíjẹ́ òtítọ́ èdidì tẹ́mpìlì tí ó ṣe àlábápín pẹ̀lú ìyàwó àti ẹbí rẹ̀.

Ẹ̀mí náà ti fún un ní ìdánilójú tipẹ́tipẹ́ tẹ́lẹ̀ pé inúrere rẹ̀ àti ìgbàgbọ́ ti mú un yege fún ìpadàlọ sí ilé ọ̀run níbi tí a ó ti rántí rẹ̀ bíi ìyanu ọmọ ìlérí àti tí a ó kíi káàbọ̀ sí ilé pẹ̀lú bíbu ọlá fún.

Fún bàbá mi, èyíinì ju ìrètí lọ. Ẹ̀mí Mímọ́ ti mu kí ó jẹ́ òtítọ́ fún un.

Báyìí, àwọn kan lè sọ pé àwọn ọ̀rọ̀ rẹ̀ àti àwọn àwòrán inú rẹ̀ nípa ilé kan ní ọ̀run kàn jẹ́ dídá ara ẹni ní inú dún ni, ìkuùkù ìdájọ́ ti ọkọ ní àsìkò àdánù rẹ̀. Ṣùgbọ́n ó mọ òtítọ́ ayéraye ní ọ̀nà kanṣoṣo tí ẹ lè mọ̀ọ́.

Ó jẹ́ onímọ̀ ìjìnlẹ̀ Sáyẹ́nsì ẹnití ó nwá òtítọ́ kiri nípa ayé ti ara ní gbogbo ìgbé ayé àgbà rẹ̀. Ó lo àwọn ohun èlò ti ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ dára tó bẹ́ẹ̀ láti gba ìyìn àwọn akẹ́gbẹ́ rẹ̀ káàkiri ayé. Ọ̀pọ̀ nínú ohun tí ó ṣe nínú ìmọ̀ ẹ̀kọ́ Apòògùn (Kẹ́místrì) wá nínú rírí iyè inú rẹ̀ nínú ojú ìwò tí ó ńrìn nípa àti pé nígbànáà fífi ẹsẹ̀ ìran rẹ̀ múlẹ̀ nípa àyẹ̀wò nínú ilé àyẹ̀wò kan.

Ṣùgbọ́n ó ti tẹ̀lé ọ̀nà tí ó yàtọ̀ láti ṣe àwárí àwọn òtítọ́ tí ó ṣe kókó jù síi àti sí ọ̀kọ̀ọ̀kan wa. Nípa Ẹ̀mí Mímọ́ nìkan ni a lè rí àwọn ènìyàn àti àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ bí Ọlọ́run ti rí wọn.

Ẹ̀bùn yìí ntẹ́síwájú nínú ilé ìwòsàn lẹ́hìn tí ìyàwó rẹ̀ ti kú. A kó àwọn ohun ìyá mi jọ láti kó lọ sílé. Bàbá dúró láti dúpẹ́ lọ́wọ́ gbogbo àwọn olùtọ́jú aláìsàn àti dókítà tí a pàdé ní ọ̀nà wa jáde lọ sí inú ọkọ̀. Mo rántí pé mo ní ìmọ̀lára, pẹ̀lú ìbínú díẹ̀, pé a gbọ́dọ̀ kúrò kí a lé dá wà pẹ̀lú ọ̀fọ̀ wa.

Mo da mọ̀ báyìí pé ó rí àwọn ohun tí ó jẹ́ pé Ẹ̀mí Mímọ́ nìkan ni ó le fi hàn án. Ó rí àwọn ènìyàn wọnnì bíi ángẹ́lì tí Ọlọ́run rán láti tọ́jú àyànfẹ́ ọkàn rẹ̀ . Wọ́n lè ti rí ara wọn bíi onísẹ́ ìlera akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ , ṣùgbọ́n Bàbá ndúpẹ́ lọ́wọ́ wọn fún iṣẹ́ wọn ní ìdúrófún Olùgbàla.

Agbára ti Ẹ̀mí Mímọ́ tẹ̀síwájú pẹ̀lú rẹ̀ bí a ti dé ilé àwọn òbí mi. A sọ̀rọ̀ fún ìṣẹ́jú díẹ̀ ní yàrá ìgbàlejò. Bàbá tọrọ ààyè láti lọ sínú yàrá ibusùn rẹ̀ tí ó wà nítosí.

Lẹ́hìn ìṣẹ́jú díẹ̀, òun rìn padà sínú yàrá ìgbàlejò. Ó ní ẹ̀rín tó dùnmọ́ni. Ó rìn wá sí ọ̀dọ̀ wa ó sì sọ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ pé, “Mo ní ìdààmú pé Mildred yíò dé inú ayé ẹ̀mí ní òun nìkan. Mo rò pé ó lè ní ìmọ̀lára jíjùnù láàrin àwọn èrò.”

Nígbànáà ó sọ yékéyéké pé, “mo gbàdúrà láìpẹ́ nísisìyìí . Mo mọ pé Mildred wà dáadáa. Ìyá mi wà níbẹ̀ láti pàdé rẹ̀.”

Mo rántí rírẹ̀rìn bí ó ṣe sọ bẹ́ẹ̀ , ní fífi ojú inú wo ìyá bàbá mi, na àwọn ẹsẹ̀ rẹ̀ kúkúrú síwájú, tí ó nsáré láàrin àwọn èrò púpọ̀ láti ri dájú pé òun wà níbẹ̀ láti pàdé àti láti dìmọ́ ìyàwóọmọ-rẹ̀ bí ó ṣe dé.

Báyìí, ọ̀kan lára àwọn èrèdí tí bàbá mi fi bèèrè fún àti tí ó fi gba ìtùnú náà ni nítorítí ó ti máa nfi ìgbà gbogbo gbàdúrà nínú ìgbàgbọ́ láti ìgbà èwe rẹ̀. Ó ti mọ̀ ọ lára láti máa gba ìdáhùn tí ó wá sí ọkàn rẹ̀ láti fún ní ìtùnú àti ìdarí Ní àfikún sí níní ìwà àdúrà, ó mọ àwọn ìwé mímọ́ àti àwọn ọ̀rọ̀ ti àwọn wòlíì alààyè. Nítorínáà ó dá àwọn ìsọ̀rọ̀ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ ti Ẹ̀mí mọ̀, èyí ti ẹ̀yin ti le ní ìmọ̀ara rẹ̀ lóní.

Ojúgbà ti Ẹ̀mí ti ṣe ju ìtùnú àti ìtọ́sọ́nà fún un . Ó yíi padà nípasẹ̀ Ètùtù ti Jésù Krístì. Nígbàtí a bá tẹ́wọ́gba ìlérí ti níní Ẹ̀mí pẹ̀lú wa nígbàgbogbo, Olùgbàlà lè fúnwa ní ìyàsímímọ́ tí a nílò fún ìyè ayérayé, ẹ̀bùn tí ó tóbijù nínú gbogbo àwọn ẹ̀bùn Ọlọ́run ( rí D&C 14:7).

Ẹ rántí àwọn ọ̀rọ̀ Olùgbàlà: “Nísisìyí èyí ni àṣẹ náà: Ẹronúpìwàdàgbogboẹyinìkangunayéẹsìwásíọdọmikí a sì rì yín bọmi ní orúkọ mi kí ẹyinódimímọníPagbígbaẸmíMímọkíẹyinólèdúróníàìlábàwọnníwájúminíọjọìkẹhìn” (3 Nephi 27:20).

Àwọn ọ̀fin wọ̃nnì wá pẹ̀lú ìlérí yí láti ọ̀dọ̀ Olúwa:

“Àti nísisìyí , lõtọ́, lõtọ́, ni mo wí fún un yín, gbé ìgbẹ́kẹ̀lé rẹ lé Ẹ̀mí èyí tí yíò darí rẹ láti ṣe rere—bẹ́ẹ̀ni, láti ṣe òtítọ́, láti rìn ní ìrẹ̀lẹ̀, láti dájọ́ ní òdodo; èyí sì ni Ẹ̀mí mi.

“Lõtọ́, lõtọ́, ni mo wí fún un yín, èmi yíò pín fún yín lára ẹ̀mí mi , èyí tí yíò tan ìmọ́lẹ̀ sí inú yín , èyí tí yíò kún ẹ̀mí yín pẹ̀lú ayọ̀” ( D&C 11:12–13).

Mo jẹ́ ẹ̀rí mi síi yín pé Ọlọ́run Bàbá wà láàyè, pé Jésù Krístì tí ó jíinde ndarí Ìjọ Rẹ̀, pé Ààrẹ Thomas S. Monson di gbogbo àwọn kọ́kọ́rọ́ oyèàlùfáà mú, àti pé ìfihàn nípasẹ̀ Ẹ̀mí Mímọ́ nṣe ìtọ́sọ́nà àti ìmúdúró Ìjọ ti Jésù Krísti ti Àwọn Ènìyàn Mímọ́ Ọjọ́ Ìkẹhìn àti àwọn onírẹ̀lẹ̀ ọmọ ìjọ rẹ̀.

Mo tún jẹ́rí síi yín síwájú síi pé àwọn arákùnrin oníyanu tí wọn ti ńbá wa sọ̀rọ̀ lónìí bíi àwọn ẹlẹ́rí Olúwa Jésù Krístì, gẹ́gẹ́bí àwọn ọmọ ẹgbẹ́ Iyejú Àwọn Àpọ́stélì Méjìlá, ni ìpè wọn jẹ́ lati ọ̀dọ̀ Ọlọ́run. Mo mọ̀ pé Ẹ̀mí ló darí Ààrẹ Monson láti pè wọ́n. Àti pé bí ẹ bá ṣe nfetísílẹ̀ sí wọn àti àwọn ẹ̀rí wọn, Ẹ̀mí Mímọ́ yíò fi ẹsẹ̀ ohun tí mò nsọ fún yín báyìí múlẹ̀ síi yín. Ọlọ́run ni ó pè wọ́n. Mo ṣe ìmúdúró wọn, mo fẹ́ràn wọn mo sì mọ̀ pé Olúwa fẹ́ràn wọn àti pé yíò ṣe ìmúdúró wọn nínú iṣẹ́ ìsìn wọn. Mo sì ṣe bẹ́ẹ̀ ní orúkọ Jésù Krístì, àmín.

**ÀWỌN ÀKỌSSÍLẸ̀ RÁŃPẸ́**

1. *Ìwé Ìléwọ́ Ìkejì Ṣíṣe àkóso Ìjọ* (2010), 20.3.10.
2. Wo George Q. Cannon, nínú “Ìròhìn àwọn ohun tí a ṣe nínú ìpàdé Gbogbo kan,” *Millennial Star,* May 2, 1863, 275–76.

© 2015 Láti Ọwọ́ Intellectual Reserve, Inc. All rights reserved. A tẹ̀ẹ́ ní USA. Àṣẹ Gẹ̀ẹ́sì: 6/15. Àṣẹ ìtumọ̀: 6/15.
Ìtumọ̀ ti *Visiting Teaching Message, November 2015.* Yoruba. 12591 779